# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸ́LẸ̀

## GBÍGBỌ́N NÍ ÌLỌPO MẸWA

## Ìtàn ...

**Danieli 1:1-21**

Ní àkókò tí ọba Nebukadnessari do ti ilu Jerusalẹmu, ẹgbẹgbẹrun awọn Ju ni a ko lọ sí ìgbèkùn sí Babiloni. Ọba sọ fun Aṣpenasi ìránṣẹ́ rẹ, lati yàn awọn ọkunrin tó ní ẹ̀bùn lára àwọn ìgbèkùn Ju ti wọn yio ma a wá si ààfin ọba fun ọdun mẹta lati kọ èdè ati ọgbọ́n Babiloni ki wọn ki o le jẹ ìránṣẹ́ fun ọba.

Danieli, Hananiah, Miṣaeli, ati Asariah ni o wu Aṣpenasi lati mu, o si mu wọn wá si ààfin ọba. Ṣùgbọ́n iṣoro kan wà. Ounjẹ tí o ní ẹran pẹlu waini tí ọba yàn fun awọn ọdọmọkunrin wọnyi, ní o ní ounjẹ ti ọ̀rọ̀ Ọlọrun kò faramọ́.



Kí Danieli ma ba di alaimore, Danieli bèrè boya oun ati awọn ọ̀rẹ́ oun mẹta iyoku le ri ounjẹ tí kò ní ẹran ati eso fun ounjẹ wọn pẹlu omi fun mimu. Ìranṣẹ ọba kò kọ́kọ́ gbà fun wọn. Ìwẹ̀fà ọba kigbe pé "Ẹ kò le ni ìlera bi ẹ ba njẹ irú ounjẹ wọnyi. Ẹ o se àìsan, bẹẹni ọba yio ke ori mi." Ṣùgbọ́n Danieli rọra sọ fun un pe ki o dan awọn wò fun ìwọ̀n ọjọ́ mẹwa, lẹhin naa ki o si wo ojú awọn niwaju rẹ ki o si tun wo ojú awọn to njẹ ounjẹ adidun ọba.

Bẹ́ẹ̀ ni o gbà fun wọn, wọn si jẹ ounjẹ laini ẹran pẹlu omi fun ijọ́ mẹwa. Ni opin ọjọ́ kẹwa naa, Danieli ati awọn ọ̀rẹ́ rẹ mẹtẹta "sanra ju gbogbo awọn ti njẹ ounjẹ adídùn ọba lọ." Danieli ẹ́:ẹ́ú.

Lẹ́hìn ọdun mẹta, a dán awọn ọmọkunrin mẹrẹrin yi wò lati ọwọ́ Nebukadnessari, o ri wọn pé ni ìwọ̀n ìgbà mẹwa, wọn sàn ju gbogbo awọn amoye ati ọlọgbọ́n ti o wà ni gbogbo ilẹ̀ ijọba rẹ̀ lọ. Bibeli fi ye wa pé Danieli lo ọgọrun ọdun láyé. Kinni ohun to se iranlọwọ fun Danieli ati awọn ọ̀rẹ́ rẹ mẹtẹta ti o si fun wọn ni ọgbọ́n, ìlera, ati ẹ̀mí gigun?

AMAZING FACTS

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọọkan tán.

1. Iru ounjẹ wo ni Ọlọrun kọ́kọ́ sẹda fun awọn enìyàn?
**Genesisi 1:29**
Ọlọrun si wipe, kiyesi i, Mo fi eweko gbogbo ti o wà lori ilẹ gbogbo ti nso ______ fun nyin, ati igi gbogbo ninu eyiti iṣe igi ______ti nso; ẹnyin ni yio ṣe ounjẹ fun.
Àkíyèsí: Ọ̀rọ̀ yí "ẹran" tumọ si "ounjẹ"

2. Lẹhin ìgbàti Adamu ati Efa ti dẹ́ṣẹ̀, ounjẹ wo li Ọlọrun tun fi kún ounjẹ wọn?
**Genesisi 3:18**
Ẹgún oun oṣuṣu ni yio ma hù jade fun ọ, iwọ o si ma jẹ ______ ______ igbẹ;
Àkíyèsí: Ounjẹ akọ́kọ́ fun awọn eniyàn ni ounjẹ ti kò ni ẹran ti iṣe eso, ohun ọgbin. Ọlọrun fi eweko ìgbẹ́ kun ounjẹ Adamu ati Efa lẹhin ìgbàtí ẹ̀ṣẹ̀ wọlé, wọn kò si le e jẹ ninu eso igi ìyè.

3. Njẹ ilera ara wa kan Ọlọrun bí?
**Matteu 4:23**
Jesu si rìn ni gbogbo ẹkùn Galili, o nkọni ni sinagogu wọn, o si nwaasu ihinrere ijọba, o si nṣe ______ ______ gbogbo ărun ati gbogbo àìsàn li ara awọn eniyàn.
**3 Johannu 2**
Olufẹ, emi ngbadura pe ninu ohun gbogbo ki o le maa ______ ______ fun ọ, ki o si maa wà ni ______ ______ , ani bi o ti dara fun ọkàn rẹ.
Àkíyèsí: Bibeli kọ wa pe, ilera ara wa se pàtàkì si Ọlọrun gidigidi. Jesu nwo awọn enìyàn san gẹ́gẹ́ bi O ti nkọ́ni. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹsẹ ati ìlànà ninu Bibeli li a le lò lati fi mu ki a wà ni ilera ati ki ọjọ́ ayé wa gùn.

4. Ọlọrun seleri fun awọn ọmọ Israeli pe bi wọn ba sin Oun ti wọn ba si gbọ́ràn, Oun yio mu àìsàn kuro laarin wọn. Se Ọlọrun mu ileri Rẹ ṣẹ?
**Orin Dafidi 105:37**
O si mu wọn jade, ti awọn ti fadaka ati wura: kò si sì ______ ______ kan ninu ẹ̀yà rẹ̀.
Àkíyèsí: Ronú bí ó ti rí! Nigbati awọn eniyàn Ọlọrun de ilẹ̀-ileri, kò sí alaisàn tabi ààrùn kan ni gbogbo orilẹ̀-èdè wọn.

5. Kilo dé ti ilera wa fi se pàtàkì si Ọlọrun tobẹ́ẹ̀?
**1 Korinti 6:19,20**
Tabi, ẹnyin kò mọ pe ara nyin ni ______ ______ Ẹmi Mimọ́, ti mbẹ ninu nyin, ti ẹnyin ti gbà lọwọ Ọlọrun? ẹnyin kì si iṣe ti ara nyin? Nitori a ti rà nyin ni iye kan: nitori naa ẹ yin Ọlọrun logo ninu ______ ______ nyin, ati ninu ẹmí nyin, ti iṣe ti Ọlọrun.
**Romu 12:1**
NITORI naa mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀ nyin, ará, ki ẹnyin ki o fi ______ ______nyin fun Ọlọrun li ẹbọ aaye, ______ ______ , itẹwọgbà, eyi ni iṣẹ-isìn nyin ti o tọ̀nà.
Àkíyèsí: Ọlọrun fẹ́ ki àgọ́ ara wa jẹ ibùgbe mímọ́ fun Oun. Nitori ìdi eyi ni a fi gbọdọ̀ yàn lati mu ki ara wa wà ni ilera pípé fun Ọlọrun lati fi ṣe ibùgbé.





6. Kinni ìlànà Bibeli ti o wà fun ìgbe-ayé ilera pípé?
**1 Korinti 10:31**
Nitori naa bi ẹnyin ba ______ ______, tabi bi ẹnyin ba ______ ______ , tabi ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ maa ṣe gbogbo wọn fun ogo Ọlọrun.
Àkíyèsí: A gbọdọ sa gbogbo ipá wa lati wà láàyè, kí gbogbo ọ̀nà ti a ngbà - má a ounjẹ ati mimu - lè má á fi ògo fún Ọlọrun.

7. Se o yẹ ki Kristiani ma a mu ọti lile?
**Owe 20:1**
ẸLẸYA li ọti-waini, ______ ______ li ọti ______ ______ , ẹnikẹni ti a ba fi tanjẹ kò gbọ́n.
Àkíyèsí: Ọti lile jẹ ohun ti Bibeli lodi si. Ọ̀rọ̀ yi "waini" ninu Bibeli le e tumọ si girapu kíkan tabi eyi ti kò kan. Otitọ kannan fun "ẹider" loni. Owe ẹ̀é:ẹ̀ọ́ọ́ẹ̀ sọ nipa bi Bibeli se juwe waini kikan, Ọlọrun sọ wípé a kò gbọdọ wo ojú rẹ̀! Waini kan ṣoṣo ti Kristiani gbọdọ̀ lo ni "waini titun," ti ki iṣe kikan, omi girapu dídùn.
**Isaiah 65:8**
Bayi ni OLUWA wi, gẹgẹ bi a ti iri ọti-waini titun ninu ìdi eso àjàrà, ti a si nwipe, Máṣe bà a jẹ nitori ibukun mbẹ ninu rẹ̀: bẹ́ẹ̀li emi o ṣe nitori awọn iranṣẹ mi, ki emi ki o má ba pa gbogbo wọn run.

8. Kinni Ọlọrun yio se fun awọn ti wọn bá ba ara wọn jẹ́?
**1 Korinti 3:16,17**
Ẹnyin kò mọ pe tẹmpili Ọlọrun li ẹnyin iṣe, ati pe Ẹmi Ọlọrun ngbe inu nyin? Bi ẹnikan bá ba tẹmpili Ọlọrun jẹ, oun ni Ọlọrun yio ______ ______; nitori pe mímọ́ ni tẹmpili Ọlọrun, eyiti ẹnyin jẹ.
**Eksodu 20:13**
Iwọ kò gbọdọ______ ______ .
Àkíyèsí: Ohunkohun tabi iṣe ti kò dara fun ilera wa ti o npawa lara tabi ti o nké ẹmí wa kúrú ni a gbọdọ pati sapakan. Ọ̀nà tabi ìpele ti o wu tí a gbà lati pa ènìyàn, ìpàniyàn naa ni. Ẹyí pẹlu oogun olóró (bi tábà ni oniruuru) ati ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun mimu ti o ni ohun oloro kafeni ninú. Ọlọrun sọ pé Oun yio pa awọn ti wọn mọ̀ ọ́n mọ̀ ba tẹmpili ara wọn jẹ́ run.

9. Irú ẹranko wo ni Ọlọrun gba awa eniyàn láàyè lati jẹ?
**Lefitiku 11:3**
Ohunkohun ti o ba yà ______ , ti o si là li ẹsẹ̀, ti o si njẹ ______ , ninu ẹran, oun ni ki ẹnyin ki o ma jẹ.
Àkíyèsí: Lati mu nkan rọrùn fun wa, Ọlọrun ti gbé ohun ẹlẹmi si ipele kan ninu ipele meji: mímọ́ ati alaimọ́. Ọlọrun fun wa laaye lati jẹ ninu awọn mímọ́ ṣùgbọ́n Ọlọrun ti sọ pe ohun alaimọ́ kò dara fun ounjẹ. Gbogbo ẹranko ti o mọ́ ni wọn ni amuyẹ meji yi: Wọn gbọdọ: (ẹ̀) yà bàtà-ẹsẹ̀, ati pe (ẹ̀) wọn a má a jẹ apọjẹ. Fun apẹrẹ, ẹlẹ́dẹ̀ yà bàtà ẹsẹ ṣùgbọ́n kò jẹ apọjẹ, nitori naa, o jẹ alaimọ́.

10. Irú ẹja ati ohun to ngbé inú odò wo lo jẹ́ mímọ́?
**Lefitiku 11:9**
Wọnyi ni ki ẹnyin ki o ma jẹ ninu gbogbo ohun ti mbẹ ninu omi: ohunkohun ti o ba ní ______ ati ______ , ninu omi, ninu okun, ati ninu odò, awọn ni ki ẹnyin ki o ma jẹ.
Àkíyèsí: Púpọ̀ nínú ẹja ni mímọ́ fún ounjẹ. Sibẹ̀, ẹja tin-in-rin bi ejò, aborí ati ẹja to jọ olongbo ni a kò gbọdọ̀ jẹ. Gbogbo ẹda to wà ninu omi ti kò ni lẹbẹ ati ipẹ́ jẹ alaimọ́, a kò si gbọdọ jẹ wọn. Apẹrẹ ni ijapa, konkọ, ọ̀pọ̀lọ́, alákàn ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.



YOR-SP20.indd 1

12/13/12 2:58 PM

11. Awọn ẹyẹ wo ni alaimọ́?
**Lefitiku 11:15,16**
Ati gbogbo ìwo li oniruuru rẹ̀, Ati __________ , ati __________ , ati ẹlulu, ati àwòdì li oniruuru rẹ̀.

Àkíyèsí: Awọn orukọ ti a dá nínú Lefitiku ẹ́ẹ́ sọ pe ẹyẹ ti akẹgbẹ rẹ ma npa-jẹ, àti eyi to ma njẹ ẹja jẹ́ alaimọ́. Siwaju sí, awọn ẹyẹ to nwa ounjẹ funrararẹ wọn bi kueli, adiyẹ ati tòlótòló wọn jẹ mímọ́.

12. Njẹ ofin nipa ẹran mímọ́ ati alaimọ́ wà lara òfin Mose ti o dopin lorí agbelebu bí?
**Genesisi 7:1,2**
OLUWA si wi fun Noa pe, iwọ wá, ati gbogbo awọn ara ile rẹ sinu ọkọ̀, nitori iwọ ni mo ri li olododo niwaju mi ni iran yi, Ninu oniruuru ẹran ti o _______ meje meje ni ki iwọ ki o mu wọn, ati akọ ati abo rẹ; ati ninu ẹran ti _______ _______ meji meji, ati akọ ati abo rẹ̀.

Àkíyèsí: Rárá, Ọlọrun ti pin ẹran sí mímọ́ ati aimọ́ lati ìbẹ̀rẹ̀ ayé. A sọ fun Noa lati mu ẹran mímọ́ wọ inu ọkọ̀ ni meje meje ati alaimọ́ ni meji meji. Èyí ti wà ki òfin Mose to dé.

13. Njẹ Ọlọrun sọ pé jijẹ ounjẹ àimọ́ jẹ ẹ̀sùn nlá bi?
**Isaiah 66:15,17**
Nitori, kiyesi i, OLUWA mbọ __________ ti oun ti iná, ati awọn kẹkẹ́ rẹ̀ bi aajà, lati fi irunu ṣẹsan ibinu rẹ̀, ati ibawi rẹ̀ nipa ọwọ́ iná, Awọn ti o ya ara wọn si mímọ́, ti nwọn si sọ ara wọn di mímọ́ ninu agbala wọnni, ti ọkan tẹle ekeji li aarin, nwọn njẹ ẹran __________ , ati ohun irira, ati eku, awọn li a o __________ pọ̀; li OLUWA wí.

Àkíyèsí: Bẹ́ẹ̀ni! Bibeli ṣe kedere ti a kò le e sì túmọ̀. Ni ipadabọ Rẹ̀ lẹẹkeji, Oluwa yio pa awọn ti o mọ ohun ti ọ̀rọ̀ Rẹ̀ nbèrè run ṣùgbọ́n síbẹ̀ ti wọn si njẹ ẹran ẹlẹ́dẹ̀ ati awọn ounjẹ alaimọ́ miran.

14. Kinni ìlànà ilera rere fun awọn Kristiani?
**1 Korinti 9:25**
Ati olukuluku ẹniti njijàdu ati bori a ma ni __________ ninu ohun gbogbo. Njẹ nwọn nṣe e lati gbà adé idibajẹ; ṣùgbọ́n awa eyi ti ki idibajẹ.

Àkíyèsí: Yíyagò fún ọti líle túmọ̀ sí kikọ ohun tó ní oró sílẹ̀ pátápátá ati lílo iwọnba ninu ohun to dára.

15. Njẹ́ a ti ma nlo ìlànà ìlera tí ó wà nínú Bibeli loni bí?
A. Ètò lati kápá ààrùn to ma nràn, nípa yíyàsọ́tọ̀ (Lefitiku 13:46)
B. Bibo ìgbọ́nsẹ̀ ẹni mọ́lẹ̀ (Deuteronomi 23:12,13)
D. Wíwẹ ara ati fifọ aṣọ lati kápá kòkòrò (Lefitiku 17:15,16)
E. Igbe aye ọmọluabi lati dènà kòkòrò tí a le kó lati ibi ìbálòpọ̀ (Lefitiku 18, Owe 5:1-12; Kolosse 3:5,6).
Ẹ. A kò gbọdọ jẹ ọ̀rá ẹran (Lefitiku 3:17, 7:22-24).
F. Ikorira ati owú jẹ́ àkóbá fun ilera ènìyàn (Lefitiku 19:17,18; Owe 15:17; Heberu 12:14,15).
G. Ounjẹ àjẹjù léwu (Owe 23:2).
GB. Àgọ́ ara wa nílò isinmi dáradára (Orin Dafidi 127:2; Marku 6:31).
I. Pàtàkì iṣẹ́ síṣe (Eksodu 20:9,10; 2 Tessalonika 3:10).
J. Inú-dídùn ni imularada rere (Owe 17:22; 1 Timoteu 6:6).
K. Ìwà awọn obi ni ipa lori awọn ọmọ (Deuteronomi 12:25; Eksodu 20:5).



Àkíyèsí: Ìlànà fún ilera ti Ọlọrun fi fún àwọn ènìyàn Rẹ̀ ni àìmoye ẹgbẹrun ọdun sẹ́hìn ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sayẹnsi fi ye wa pé ìlànà náà ti wà síwájú àwọn ènìyàn náà. Kò pẹ́ púpọ̀ ti a mọ pe awọn ìlànà yi ni èrè púpọ̀ ti wọn nṣe fun wa!

16. Njẹ awọn ènìyàn tí yóò wà ni ọ̀run yo ma pa ẹran jẹ bí?
**Isaiah 65:25**
Ikooko ati ọdọ-agutan yio jumọ jẹ pọ̀, kiniun yio si jẹ koriko bi akọ-malu: erupẹ ni yio jẹ ounjẹ ejò. Nwọn kì yio _____ __, tabi ki nwọn ______ _ ni gbogbo oke mímọ́ mi, li OLUWA wi.
**Ifihan 21:4**
Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li ojú wọn; ki yio sì sí _______ mọ́, tabi ọfọ, tabi ẹkún, bẹ́ẹ̀ni ki yio si irora mọ́: nitori pe ohun atijọ ti kọja lọ.

Àkíyèsí: Ohun gbogbo ti Adamu ati Efa ti sọnu nigbati ẹ̀ṣẹ̀ wọle ni a o da padà ni ijọba Ọlọrun titun, ati ounjẹ àkọ́kọ́ ti ki ini ẹran. Kò ní sí pípa tabi fifa ẹran ya ni ayé titun.

17. Bawo ni mo ṣe le yí ounjẹ ati ilera mi pada ti yio sì wu Oluwa?
**Esekieli 11:18-20**
Nwọn o si wá sibẹ, nwọn o si _______ gbogbo ohun irira rẹ̀ ati gbogbo ohun eeri rẹ̀ kuro nibẹ, Emi o si fun wọn li ọkàn kan, emi o si fi ẹmi _____ __ sinu nyin; emi o si mu ọkàn okuta kuro lara wọn, emi o si fun wọn li ọkàn ẹran: Ki nwọn le rìn ninu aṣẹ mi, ki nwọn si le pa ilana mi mọ, ki nwọn si ṣe wọn: nwọn o si jẹ eniyan mi, emi o si jẹ Ọlọrun wọn.

Àkíyèsí: Bi a ba pinnu lati pa òfin ilera Ọlọrun mọ, Ọlọrun yio fi ẹmi titun sinu wa, èyí ti yio fun wa lagbara ti a nilo lati gbe igbé ayé ilera pípé (Johannu 1:12).

# Èsì Rẹ

Ọlọrun bọla fun Danieli ati awọn ọ̀rẹ́ rẹ nitori pe wọn pa òfin ìlera mọ́, èyí ti iṣe pàtàkì ninu ìgbé ayé Kristiani. Njẹ o fẹ́ lati tẹle ìlànà ilera ti inú ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ki o si se ara rẹ ni tẹmpili mímọ́ nibiti Ẹmí Mímọ́ le ma a gbé bí?

ÌDÁHÙN:____________________

# Àfikún

Ipele yìí pèsè awọn irohìn afikún fun ikẹkọ síwajú si.

Ìtumọ̀ ìran Peteru

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn lo nlo ìran gọgọwu nla ti Peteru rí (Iṣe Awọn Aposteli 10:9-28) lati da ara wọn láre fún jíjẹ ẹran àìmọ́. Wọn nwipe eyi túmọ̀ si pe Jesu kọ́ awọn ọmọ-ẹhin Rẹ pe o se itẹwọgbà lati jẹ oniruuru ẹran alààyè.

Bí ó ti wù kí o rí, nígbàtí gọgọwu naa ba sọkalẹ ti a si wí fún Peteru ki o pa ki o si maa jẹ awọn ẹran àìmọ́, èsì rẹ ni, "Rárá agbẹdọ, Oluwa, nitori emi kò jẹ ohun èèwọ̀ ati aláìmọ́ kan rí." Iṣe Awọn Aposteli 10:14. Kiyesi pe lẹhin ọdun mẹta ààbọ̀ ti Peteru ti gbọ ẹ̀kọ́ Jesu, Peteru kò gba òye kankan tabi ìwúrí nipa pe ààyè wà fun jijẹ ounjẹ àìmọ. O tún jẹ ayọ̀ pe nínú ìran náà Peteru kò mu ọkan jẹ lati inu gọgọwu nlá náà.

Ìran Peteru ki iṣe lati ya àwọn ẹran àìmọ́ sí mímọ́ rárá. Peteru funọ́ rara rẹ ṣe àlàyé ìran naa ni ẹsẹ ikejidinlọgbọn (28): "Ọlọrun ti fi hàn mi pe, ki emi ki o máṣe pe ẹnikẹni li èèwọ̀ tabi aláìmọ́." Lẹẹkan si ni ẹsẹ ikẹrinlelọgbọn (34), Peteru se akojọpọ̀ kókó ìran rẹ nigbati o sọ pe, "Nitootọ mo woye pe, Ọlọrun ki iṣe ojusaaju ènìyàn."

Ọ̀rọ̀ Ọlọrun sí Peteru nise pẹlu wiwẹ ènìyàn mọ́ ki iṣe ẹran. Ìran yi ni a fun awọn ọmọ lẹhin ti iṣe Ju pé ki wọn maṣe pe awọn Keferi ni alaimọ́, ati pe wọn gbọdọ kede ihinrere fun gbogbo ènìyàn laye laisi ìdènà kankan.

Ṣé àdúra ma nsọ ounjẹ di mímọ́ bí?

Ìkìlọ̀ ti o wà ninu ẹ Timoteu è:ẹ́ọ́ú nipa awọn ti yio kuro ninu ìgbàgbọ́ ni ìgbà ikẹhin ni o ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀kọ́ òdì - bi i titẹle awọn ẹmi eṣu, didani-lẹkun ati gbeyawo, pipaṣẹ lati yàgò fun awọn ounjẹ kan. Bayi, ariyan-jiyàn ti dide nipa ẹsẹ kẹrin nibiti o sọ pe "Gbogbo ohun ti Ọlọrun dá li o dara." Ẹsẹ yi nsọ fun wa pé, ohun gbogbo ti Ọlọrun dá, ni a dá fun ìdí kan. Ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ ènìyàn rò wípé, ọ̀rọ̀ yi tumọ si pé, gbogbo ẹran ni a le jẹ bi a ba gbadura gidigidi sí i, ti a si yà a si mímọ́ nipaṣẹ àdúrà ọpẹ́. Èyi yio tumọ si pe bi a ba gbadura lori ẹyẹ, aáyán, ekòló tabi àdán yio sọ wọn di ounjẹ rere. Iru itumọ bayi yio jẹ eyi ti kò dara. "Ki a maṣe tan yin jẹ; a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti eniyàn ba funrugbìn, oun ni yio si ká." Galatia 6:7.

Lati dènà ìgbésẹ̀ tí kò dára, Paulu yára fi kún un pé: "Nítorí a fi ọ̀rọ̀ Ọlọrun àti àdúrà yà a sí mímọ́." 1 Timoteu 4:5. Nítori náà, Ọ̀rọ̀ Ọlọrun ní o kọ́kọ́ gbọ́dọ̀ fi ọwọ́ sí, lẹhin náà ni àdúrà ọpẹ́ yio wá yà á sí mímọ́ fún jíjẹ.

Yio ràn wa lọ́wọ́ bí a bá kíyèsí ọ̀rọ̀ yi "ẹran" nínú ojulówó èdè, kí iṣe ẹran jíjẹ nìkan. Ọ̀rọ̀ Giriki yi "broma" túmọ̀ sí "ounjẹ." A le mọ̀ pé àlàyé Paulu ki iṣe nípa ẹran àìmọ́ ti inu Bibeli, nítori pé ẹran ti awọn ẹlomiran ti sọ di èèwọ̀ ni ounjẹ "ti Ọlọrun ti dá fún ìtẹwọgbà pẹlu ọpẹ́ àwọn onigbàgbọ́ ati awọn ti o mọ òtitọ́." 1 Timoteu 4:3.

Ó rọrùn lati ri awọn ounjẹ ti Iwé Mímọ́ se apejuwe ti iṣe èyí ti Ọlọrun dá ki a si gba wọn pẹlu ọpẹ́ (Genesisi 1:29; 3:18; Léfitiku 11:1-22). A kọ ibi ayọka yi fun awọn "to gbàgbọ́ ti wọn si mọ otitọ." Ọ̀rọ̀ Ọlọrun jẹ otitọ. Awọn ti wọn "gbàgbọ ti wọn si mọ" ọ̀rọ̀ Rẹ yio dari wọn si awọn nkan naa ti a ti "yà sí mímọ́" ati àwọn ti a dá "lati gbà pẹlu ọpẹ́." Awọn ti wọn "yà ara wọn sí mímọ́" nigbati wọn ntẹsiwaju lati ma a jẹ ẹran àìmọ́ ni a o parun ni bíbọ̀ Jesu lẹẹkeji (Isaiah 66:15-17).

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678



YOR-SP20.indd 2 12/13/12 2:58 PM